IB DIPLOMA PROGRAMME
PROGRAMME DU DIPLÔME DU BI
PROGRAMA DEL DIPLOMA DEL BI

# YORUBA A1 – STANDARD LEVEL – PAPER 1
# YORUBA A1 – NIVEAU MOYEN – ÉPREUVE 1
# YORUBA A1 – NIVEL MEDIO – PRUEBA 1

Tuesday 21 May 2002 (afternoon)
Mardi 21 mai 2002 (après-midi)
Martes 21 de mayo de 2002 (tarde)

1 hour 30 minutes / 1 heure 30 minutes / 1 hora 30 minutos

## INSTRUCTIONS TO CANDIDATES

- Do not open this examination paper until instructed to do so.
- Write a commentary on one passage only. It is not compulsory for you to respond directly to the guiding questions provided. However, you may use them if you wish.

## INSTRUCTIONS DESTINÉES AUX CANDIDATS

- Ne pas ouvrir cette épreuve avant d'y être autorisé.
- Rédiger un commentaire sur un seul des passages. Le commentaire ne doit pas nécessairement répondre aux questions d'orientation fournies. Vous pouvez toutefois les utiliser si vous le désirez.

## INSTRUCCIONES PARA LOS ALUMNOS

- No abra esta prueba hasta que se lo autoricen.
- Escriba un comentario sobre un solo fragmento. No es obligatorio responder directamente a las preguntas que se ofrecen a modo de guía. Sin embargo, puede usarlas si lo desea.

*Kọ àgbọ́yé àti àlàyé è rẹ lórí ọ̀kan nínú àwọn àyọkà wọ̀nyí.*

**1.** (a)

'Nigba ti igbagbọ de Ọ̀wọ ni ọlàjù wọ Ọ̀wọ. Ohun tí ó sì jẹ pataki olori ọlàjú wa yìí ni ile-iwe ti a ń rán awọn ọmọ wa wọnyì ni ọ̀kọ̀ọ̀kan ṣugbọn anfaani ti a ̄lérò pé a ó máa rí ninu ẹ̀kọ́ awọn ọmọ wa kọ́ ni a ń rí yìí. Lóòótọ́, àṣà oyinbo ni a fi ń kọ́ awọn ọmọ wa ni ilé-ẹ̀kọ́ ṣugbọn àgbàsódì ni awọn ọmọ wa gba àṣà náà. Tí a bá kiyesi awọn oyinbo ti à ń rí, a ó ri i wi pe bí ìgbín fà, ìkarahun a tẹ̀le é ni wọn pẹlu ọkọ ati iyawo. Wọn ìbáà máa lọ tọ̀, wọn ìbáà máa lọ ṣu, wọn kò ní í ya ara wọn. Wọn tilẹ bá a dé ibi kí wọn máa fá ara wọn lẹnu lá ti wọn bá ṣẹ̀ṣẹ̀ ti ibi iṣẹ́ dé. Àṣà a ılú tiwọn ni eyi yìí; lati kekere ni wọn sì ti ń kọ́ orísìírísìí ẹ̀kọ́ nipa ọ̀nà ti àṣà yìí kò fi ní í yí wọn lọwọ, tí kò sì fi ní í kó ìtìjú bá àwùjọ wọn.

'Bi ọmọbinrin èèbò bá ti bẹ̀rẹ̀ sí í bàlágà ni awọn obi rẹ̀ yóó ti máa kọ́ ọ bí à á tí í ṣe é ba ọmọkunrin ṣire níwọ̀n t'ó bá ojú mu, tí kò ní í mú ìpalára wa, bi awọn obi ti ń kọ́ wọn nile ni olukọ yóó máa kọ́ wọn ni ile-iwe. Bi wọn ti ń kọ́ ọkunrin ni wọn yóó máa kọ obinrin. Nitori eyi, ó ti mọ́ awọn èèbó lara lati ṣire pọ̀, ọkunrin pẹlu obinrin, bi ó ti wù wọn lâì sí ọkàn nibi ìṣekúṣe. Ti èèbó niyẹn.

Ṣugbọn n kò ṣẹ̀ṣẹ̀ le máa sọ nipa àṣà abínibí awa Yoruba. Tiwa yatọ sí ti èèbó tefétefé. A kì í jẹ́ kí iyawo-ọ̀nà lọ kí ọkọ rẹ̀ bi ó ti wù ú, a kì í jẹ ki wọn dijọ lọ sibi kan, ànì, bí wọn bá pade ara wọn lọna, iyawo-ọ̀nà nilati fi aṣọ bo ojú ni. Ó ṣeéṣe ki iyawo má mọ ọkọ rẹ̀ titi ti yóó fi wọle. N kò tun ṣẹ̀ṣẹ̀ le máa sọ awọn àṣà wọnyi fun yin mọ́. Ọmọ wo ní í dá obinrin in yànfẹ́ funrarẹ̀?" Awọn eniyan làì mọ àsìkò tí wọn sọrọ, pẹlu ohùn-arò ní, "Kò sí - - - -." "Obi wo ní í fẹ ọmọ fun ọmọ rẹ̀ lâì wádìí idile ọ̀tún ati ti òsì awọn tí ó máa jẹ àna rẹ̀ dájú kí ó

T. A. A. Ladele, *Je n lo 'Gba a Temi*, 2001

– Kí ni kókó ọ̀rọ̀ tí ó wà nínú àyokà yǐ?

– Njé o fara mọ́ èrò rẹ̀ lórí àsà òyinbó?

– Ọnà wo ni bí ó ṣe lo ọ̀rọ̀ rẹ̀ gbà wú ọ lórí?

– Sọ díẹ̀ nínú àwọn àsà Yorubá tí àyọkà yǐ rán ọ létí.

**1.** (b)

Ifá, rìn gbẹ̀rẹ̀–gbẹ̀rẹ̀
Kí o lọ́ bá mi pa gbogbo àwọn ọ̀táà mi.
Èrun ni kí ẹ bá mi
Fi run àwọn ọ̀táà mi pátápátá.
Ojú kan ṣoṣo lògìrìṣàkọ́· ọ jóko sí
Tí í́ fií rán igba iṣu lọ́ sí òde ọ̀run.
Igikígi kì í tagbò,
Kó fẹnu kan àṣórín:
Ọjọ́ tí igikígi bá fojú kan àṣórín,
Ní ọjọ́ náà ni ikú ń pa á.
Gbogbo àwọn tí ń bá mi ṣọ̀tá,
Tó bá ń fi ẹnu burúkú kàn mí,
Ifá, bá mi rán wọn lọ sí òde ọ̀run.
Àwo ni kí ẹ bá mi
Fi wọ́ wọn sí òde ọ̀run.
Àfòòfò-pa-ni làá pe oṣó.
Oṣó, fò fẹ̀ẹ̀
Kí o bá mi pa gbogbo àwọn ọ̀táà mi.
Ọ̀ṣẹ́ méjì ni kí o bá mi
Ṣẹ́gun ọ̀tá ilé àti ọ̀tá òde.

44. *A-bá-ni-ṣé-tàá*
Abániṣétàá! Abániṣètàá! Abániṣétàá! –
Orúkọ tí à á pe Ifá.
Ọlágbọ̀nràndùn–
Orúkọ tí à á pe ilẹ̀.
Adánilåre–
Orúkọ tí à á pe orí ẹni.
Àdá–fi–èèkù–ṣakin–
Orúkọ tí à á pe Ògún.
Ọkùnrin gbinrin–gbinrin bí idẹ–
Orúkọ tí à á pe Èṣù.
Ọkunrin kọ̀rọ̀bọ̀tọ̀ tíí tẹ̀pá òjé
Ni orúkọ tí à á pe àwọn òrìṣà.

P. Ade Dopamu, *Ma dari Kan*, Ofo Isegun, 2000

– Kí ni àgbọ́yé rẹ nínú ọfọ̀ yǐ?

– Ṣe àlàyé ọ̀rọ̀ lílò tí ó wú ọ lórí nínú ọfọ̀ yǐ

– Kí ni ìtumọ̀ ọfọ̀ yǐ fi yé wa pé ó wúlò fún?

– Sọ díẹ̀ nínú ọfọ̀ Yorùba tí àyokà yǐ rán ọ létí pẹ̀lú àlàyě lórí ọ̀nà tí wọn gbà ń pè é.